# KÍ NI O MỌ̀ NÍPA ÀWỌN Ọ̀NÀ ÌFÈTÒSỌ́MỌ BÍBÍ /ÍFÀYÈ-SÍLẸ̀ LÁÀRIN ỌMỌ KAN ÀTI ÒMÍRÀN?

| ÌLÀNÀ | ÀWỌN KÓKÓ ÀRÍGBÁMÚ | ÀSÌKÒ IṢỌWỌ́ṢIṢẸ́ |
|---|---|---|
| ÌFÈTÒSỌ́MỌ BÍBÍ ÒGÙN ONÍKÓRÓ  | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte tó ń ṣiṣé dáadáa, tí a ń lò lójojúmọ́<br>• Kó léwu fún obínrin kankan iye ọmọ ọdún tó wù kó jẹ́, pẹ̀lú àwọn tí wọn kò tíì bímọ rí<br>• Ìfètòsọ́mọ bíbí ògùn oníkóró tó wà fún enití ó ń fún omo lóyàn (mini pill) kó léwu fún àwọn obìrin tó ń fọ́mọ lọ́yàn nígbàkigbà lẹ́yìn tí wọ́n bá bímọ tán | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte |
| ÌFÈTÒSỌ́MỌ BÍBÍ ALÁBẸ̀RẸ̀  | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte tó ń ṣiṣé dáadáa, tó jẹ́ olóṣù méjì tàbí oṣù olóṣù mẹ́ta<br>• Kó léwu fún obínrin kankan iye ọmọ ọdún tó wù kó jẹ́, pẹ̀lú àwọn tí wọn kò tíì bímọ rí<br>• Kó léwu fún àwọn obìrin tó ń fọ́mọ lọ́yàn tọ́jọ́ orí rẹ̀ ti ju ọ̀sẹ̀ mẹ́fà lọ | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte |
| ÌFÈTÒSỌ́MỌ BÍBÍ ONÍSÀÁNÁ APÁ  | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ pípẹ́ tó ń ṣiṣé dáadáa fún bíi ọdún mẹ́ta sí márùn-ún<br>• Kó léwu fún obínrin kankan iye ọmọ ọdún tó wù kó jẹ́, pẹ̀lú àwọn tí wọn kò tíì bímọ rí<br>• Kó léwu fún àwọn obìrin tó ń fọ́mọ lọ́yàn nígbàkigbà lẹ́yìn tí wọ́n bá bímọ tán | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ pípẹ́ |
| ÌFÈTÒSỌ́MỌ BÍBÍ ONÍFISI TÍ A FI SÍ OJÚ ARA OBÌNRIN   | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ pípẹ́ tó ń ṣiṣé dáadáa fún bíi ọdún márùn-ún sí mẹ́wàá<br>• Kó léwu fún obínrin kankan iye ọmọ ọdún tó wù kó jẹ́, pẹ̀lú àwọn tí wọn kò tíì bímọ rí<br>• Kó léwu fún àwọn obìrin tó ń fọ́mọ lọ́yàn<br>A lè fi si láàarín wákàtí méjìlé láàdọ́ta sí ọ̀sẹ̀ mérin lẹ́yìn tí a bímọ tán | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ pípẹ́ |
| RỌ́BÀ ÌDÁBÒBÒ ỌKÙNRIN  | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte tó ń ṣiṣé dáadáa tí a ń lò lásìkò ìbálòpọ̀ akọ àti abo<br>• Tí a bá lòó dáadáa bó ti yẹ nígbàgbogbo, ó máa;<br>- Dènà oyún níní<br>- Dènà kíkó lára àwọn àrùn ìbálòpọ̀, títí kan àrùn HIV | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte |
| RỌ́BÀ ÌDÁBÒBÒ OBÌNRIN   | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte tó ń ṣiṣé dáadáa tí a ń lò lásìkò ìbálòpọ̀ akọ àti abo<br>• Tí a bá lòó dáadáa bó ti yẹ nígbàgbogbo, ó máa;<br>- Dènà oyún níní<br>- Dènà kíkó lára àwọn àrùn ìbálòpọ̀, títí kan àrùn HIV<br>• Kó léwu fún àwọn obìrin tó ń fọ́mọ lọ́yàn | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte |
| FÍFỌ́MỌ LỌ́YÀN NÌKAN LÁÌFI ǸKANKAN LÁÀ  | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí tó ń ṣiṣẹ́ dáadáa lẹ́yìn tí obìrin bá bímọ tán, tó sì ní àwọn àmúyẹ yìí:<br>- Wọ́n fọ́mọ lọ́yàn nìkan ṣoṣo (ní ọ̀san àti òru)<br>- Wọ́n ní ọmọ ọwọ́ tí kò tíì tó ọmọ oṣù mẹ́fà<br>- Wọ́n kò máa rí ǹkan oṣù wọn | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí ọlọ́jọ́ péréte |
| SÍSO ILÉ ỌMỌ OBÌNRIN PA   | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí tó ń ṣiṣẹ́ dáadáa fáwọn obìnrin tí wọ́n ti pinnu láti máà bí ọmọ kankan mọ́ | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí alásopa |
| TÍTẸ ỌKÙNRIN NÍ Ọ̀DÁ   | • Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí tó ń ṣiṣẹ́ dáadáa fáwọn ọkùnrin tí wọn kò fẹ́ kí ìyàwó wọn bímọ mọ́ | Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí alásopa |

© NURHI 2017

**Bèrè lọ́wọ́ akọ́ṣẹ́mọ́ṣẹ́ ìfètòsọ́mọ bíbí re nípa ìfètòsọ́mọ bíbí**

Get it together
KNOW. TALK. GO.

NURHI 2
NIGERIAN URBAN REPRODUCTIVE HEALTH INITIATIVE